# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## OSÙ KEJÌ, ỌDÚN 2022

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**(ISIN ỌRẸ AKỌSO)**

**OṢÙ KEJÌ 2021**
**KÍGBE LÒDÌ SÍ ẸMÍ SENAKÉRUBÙ**

| | |
|---|---|
| 7:00 am – 7:05 am | Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀ |
| 7:05 am – 7:20am | Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn |
| 7:20 am – 7:35 am | Ijẹ́rì |
| 7:35 am – 7:45 am | Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdágba |
| 7:45 a m – 8:45 am | Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ |
| 8:45 am - 9:00 am | Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé |

ORÍSUN IGBÀLÀ KÍKÚN! ORÍSUN IGBÀLÀ KÍKÚN

1. Orísun igbàlà kíkún
Sí sílẹ̀ fún gbogbo wa
Lát'Ọ̀dò Olùgbàlà wà
Ló nṣàn yí gbogb'ayé ká;
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

2. Ìran ológo li èyí
Ìsun ìwẹ̀nùmọ́ nṣàn,
Ó nwẹ gbogbo abàwọ́n nù,
Ti ìdálẹ́bi ẹsẹ̀,
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ẹ̀jẹ̀ tí nwẹ̀ mọ́ láúláú.

3. Ìsun ijìnlẹ̀ ìfẹ́ Rẹ
Nṣàn ní inú ọkàn wa;
Ó nwẹ gbogbo erò aìmọ́,
K'a lè wà láílàbàwọ́n,
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

4. Ìsun iyè aìnìpẹ̀kùn,
Láti ọ̀run nṣàn sí wa,
Ọlọ́run dàpọ̀ pẹ̀lú wa,
Idàpọ̀ t'ó dùn jùlọ;
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

5. Ẹ̀rù'bànújẹ́ ti fò lo,
Àníyàn òn'yèméjì,
Igbàgbọ́ kò bẹ̀rù ọ̀la
Tor'Ólúwa nṣámọnà,
Ó nṣàn síbẹ̀
Ìsun igbàlà kíkún.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Agbárákágbara tí wọ́n yàn kó fi ògo mi gba ìgbéga nínú ìjọba òkùnkùn, kí n tó kúrò níbi lónìí, ìwọ yóò kú, ní orúkọ Jésù.
2. Lónìí, nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, èmi yóò gba gbogbo ògo tímo ti sọnù nínú àwọn ọdún tóti kọjá, ní orúkọ Jésù.
3. Ohun rere yòówù nínú ayé mi tí wọ́n ti gbé sin, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, gba ìyè báyìí, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ìhàmọ́ra òkùnkùn tí wọ́n dojú rẹ̀ kọ ògo mi lọ́dún yìí, gbiná, ní orúkọ Jésù.
5. Bàbá mi, jẹ́ kí gbogbo ìdibàjẹ́ nínú ìgbé ayé ẹ̀mí mi gba agbára àjínde lònîì, ní orúkọ Jésù.
6. Nípa agbára tó pín òkun pupa sí méjì, Ọlọ́run mi yóò gbà mí kúrò nínú gbogbo ìjákulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti fa ire mu kúrò nínú ayànmọ́ mi, ṣubú lulẹ̀ kú lónìí, ní orúkọ Jésù.

<u>**ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ**</u>

## ÌJẸ́WỌ́

**Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo ìwádì sátánì láti mú ìjákulẹ̀ bá ìrìn àjò itẹ̀sìwájú mí lọ́dún yìí, fọ́ sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
4. Àwọn agbára tí wọ́n yàn láti múmi rákórò dé ilẹ̀ ìlérí mí lọ́dún yìí, gbiná, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn agbára òkùnkùn tí wọ́n gbà láti fòpin sí ayànmọ́ mi, ṣekú pa ẹni tóni ọ́, ní orúkọ Jésù.
6. Ète ọ̀tá tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi lọ́dún yìí, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, kí o sì pawọ́n run, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, jẹ́ kí ibi ìsápamọ́ sí àwọn ọ̀tá oloríkunkún mi gba iná, ní orúkọ Jésù.

<u>**ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ**</u>

**2 Krónikà 7:14-15:** Bí àwọn ènìyàn mi tí a npè orúkọ mi mọ́, bá rẹ ara wọn sílẹ̀, tí nwọ́n bá sì gbàdúrà, tí nwọ́n bá sì wá ojú mi, tí nwọ́n bá sì yípadà kúrò nínú ọnà búburú wọn; nígbàná ni èmi ó gbọ̀ láti ọ̀run wa, èmi ó sì dárí ẹ̀sẹ̀ wọn jì, èmi ó sì wo ilẹ̀ wọn sàn. Nísìsìyí ojú mi yóò ṣí, etí mi yóò sì tẹ̀ sí àdúrà ibi yìí.

**Jákọ́bù 5:15-16:** Àdúrà igbàgbọ́ yóò sì gba aláìsàn ná là, Olúwa, yóò sì gbé e dìde; bí ó bá sì ṣe pé ó ti dẹ́sẹ̀, a ó dárí jí ì. Ẹ jẹ́wọ́ ẹ̀sẹ̀ nyín fún ara yín, kí ẹ sì ma gbàdúrà fún ara nyín, kí a lè mú nyin láradá, iṣẹ́ tí àdúrà olódódo nṣe lí agbára púpọ̀.

**Òwe 3:5-8:** Fi gbogbo ayà rẹ gbẹ́kẹ̀lé Olúwa; má sì ṣè tẹ sí ìmọ̀ ara rẹ. Mọ̀ ọ̀ ní gbogbo ọ̀nà rẹ: òn ó sì ma tọ ipa-ọnà rẹ. Máṣe ọ̀lọgbọ́n lí ojú ara rẹ; bẹ̀rù Olúwa, kí o sì kúrò nínú ibi. Òn ó ṣe ìlera sí òdodo rẹ, àti ìtura sí egungun rẹ.

**Málákì 4:2:** Ṣùgbọ́n Òrùn òdodo yóò là, ti òn ti ìmúláráda ní ìyẹ́-apá rẹ, fún ẹ̀nyin tí ó bẹ̀rù orúkọ mi: ẹ̀nyin ó sì jáde lọ, ẹ̀nyin ó sì ma dàgbà bí àwọn ẹ̀gbọ̀rọ̀ màlú inú agbo.

**Máttéù 11:28:** Ẹ wá sọ́dọ̀ mi gbogbo ẹ̀nyin tí nṣiṣẹ́, tí a sì di ẹrù wúwo lé lórí, èmi ó sì fi isìmi fún nyín. Ẹ gba ajàgà mi sí ọrùn nyìn, kí ẹ sì ma kọ́ ẹ̀kọ́ lọ́dọ̀ mi; nítorí onínú tútù àti onírẹ̀lẹ̀ ọkàn li èmi; ẹ̀nyin ó sì rí isìmi fún ọkàn nyín. Nítorí ajàgà mi rọrùn, ẹrù mi sì fúyẹ́.

**Fílíppì 4:6-7:** Ẹ máṣe àníyàn ohunkóhun; ṣùgbọ́n nínú ohun gbogbo, nípa àdúrà àti ẹ̀bẹ̀ pẹ̀lú ìdúpẹ́, ẹ má fi ìbérè nyìn hán fún Ọlọ́run. Àti àláfíà Ọlọ́run, tí ó ju imọ̀ràn gbogbo lọ, yóò sọ ọkàn àti èrò nyín nínú Krístì Jésù.

**Máttéù 10:1:** Nígbàtí ó sì pé àwọn ọmọ-ẹ̀hìn rẹ méjèjìlá sí ọ̀dọ̀, ó fi agbára fún wọn lórí àwọn ẹ̀mí aìmọ́, láti ma lé wọn jáde àti láti ṣe iwòsàn gbogbo àrùn àti gbogbo aìsàn.

## ÀDÚRÀ ṢÍWÁJÚ FÍFI ỌRẸ ÀKỌ́SO SÍLẸ̀

**Na ọrẹ rẹ sókè, kí o sì gbàdúrà bàyî:**
"Bàbá, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ fún fífún mi ní anfàní, okun àti ọgbọ́n láti ní irúgbìn yìí. Pẹ̀lú ọrẹ yi, mo dámọ̀, mo si yìn Ọ́ gẹ́gẹ́ bí orísun kànṣoṣo ti ìṣúná mi. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ nítorí nígbà kan rí mo ti sọnù, ṣùgbọ́n a ti ṣàwárí mi báyìí. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ fún igbàlà ọkàn mi.
Bí mo ti n fi ọrẹ àkọ́so yì sílẹ̀ báyìí, gbà á , Olúwa, nípa agbára ẹ̀jẹ̀ Jésù. Nípa ọrẹ yìí, mo jẹ́wọ́ wí pé, Ìwọ ni olú àníyàn mi. Ọlọ́run, dìde, kí o si lo ọrẹ yì gẹ́gẹ́ bí kọ́kọ́rọ́ sí ipọ̀si, títóbi, ìgbéga àti ojúrere mi tíkò wọ́pọ̀. Nípa ọrẹ yìí, jẹ́ kí gbogbo agbára afiniṣòfò gba ìparun kúrò nínú ayé mi. Gbà mí kúrò nínú àdánù yòówù, kí O sì fi àwọn ibùkún tí owó kòlè è rà gbé ayé mi wọ̀.
Nípa ọrẹ yìí, mo so ara mi pọ̀mọ́ orísun ọ̀run tó ṣí sílẹ̀ ti ètò ìṣúná owó, alàjá tíkò wọ́pọ̀, ìṣerere tó njẹ gàba, ojúrere tíkò wọ́pọ̀, aṣèyọrí tó tayọ eròngbà àti ìṣẹ́gun pátápátá, ní orúkọ Jésù.

Bí mo ti n fi ọrẹ àkọ́so yìí sílẹ̀, jẹ́ kí agbára iyàsì-mímọ́ rẹ ṣàn sínú àwọn ètò iṣùná mí tókù. Olúwa, gbé mi wọ inú ibi, ipò, ifòròróyàn àti ọgbọ́n Rẹ fún ayé mi. Jẹ́ kí a gbin wàrà àti oyin ilẹ̀ yìí sí ókan-ayà mi.
Èyí ní mo gbàdúrà, ní orúkọ nlá Jésù Kristì Olúwa. Àmín.”